# IROHIN YORUBA

Eyin oro wa—"IWAJU L'OPA EBITI NBE SI"

VOL. IX NO. 4?? MONDAY OCTOBER 5 195? KOBO KAN (1d)

# Oba Adele Se Ajodun Kerin



Ni ojo Oj bo ti ise ojo kini osu yi ni Alaiyeluwa Adele Ke ji Oba Eko se Ajodun Kerin ti o gun ori oye.

Oba na lo se isin idupe ni Mosalasi Jimo, awon Omo-Oba l'okunrin ati l'obirin pelu awon Ijoye ati awon enia pataki pataki ninu orisirisi Egbe ilu ni o ba a lo se isin idupe na ni agogo meje abo aro.

Ngbati Oba na pada de lati ibi isin idupe na ni o pin ebun fun gbogbo awon alagbe ilu ti o wa pejo si iwaju afin re ni Iga Idunganran.

Lehin eyi ni gbogbo awon orisirisi egbe ati gbogbo enia bere si se ajoyo Ajodun na ni Afin re titi ile fi su. Ki Olorun da Oba si ki o le se opo odun si i l'aiye pelu ayo ati alafia.

## Awolowo Nse Ibewo Awon Ilu Gbogbo

IBADAN—Ni ojo Abameta ti ise ojo Kerindinlogbon osu ti o koja yi ni Oloye Obafemi Awolowo, Alakoso Ijoba Iwo-orun Nigeria bere irin ajo lati ma a se ibewo awon ilu ti o wa ni abe Ijoba Iwo-orun Nigeria.

Ninu irin ajo re ni yio se ibewo awon ilu Ijebu, Ondo, Epe, Makun, Akoko, Idanre, Ekiti, Akure, Efon Alaye, ati Owo yio si pada si aye ijoko amojuto Ise Ijoba re ni Ibadan ni ojo kewa osu yi.

## Egba Ati Ijebu F'aramo "Action Group" Lori Oran Eko

Ninu ipade Igbimo Ijoba Egba ti nwon se laipe yi ni Oloja D. S. Adegbenro nsin wa ni imoran pe o to ki Ijoba Egba fi ara mo awon Egbe Action Group lori ipinnu won pe ki ilu Eko ma se yapa kuro lara awon ilu abe Ijoba Iwo-orun Nigeria. Olola Adedamola gbe e lese. Gbogbo awon Igbimo na si fi ara mo imoran na.

Awon Oba igun merin Abeokuta ni o peju sinu ajo Igbimo ra ati Oba Olota pelu Amala, Oba Alake ni Alaga, bi nwon ti bere Ipade Igbimo na ni Oba Alake ti pe akiyesi awon Igbimo na si ofo meji ti o re won nipa iku Oloye Adeneye Titcombe Lisa Ake ati Oloye T. Somoye Ogboye Egba Christians. Awon Igbimo na si dide duro fun iseju meji pelu idake-jeje ati itesiba fun iranti won.

Wo oju ewe kerin

## Eye Idagbere Fun Kotoye Ati Akintola

Ni ojo Aje ti ise ojo kokanlelogun osu ti o koja yi ni awon Egbe Odo Afenifere, "Action Group Youth's Association" Eka ti Eko se eye idagbere fun awon Asiwaju won meji Ogbeni N. A. B. Kotoye, Alaga Egbe na ati Ogbeni Akinbowale Akintola, Akowe Egbe na ti awon ni lo fun eko-giga ni ilu Oyinbo.

Ni Gbongan Apejo Glover l'Ebiogbeti ni nwon gbe ti ijoko ase ye na si. Eniti o se Alaga Aseye na ni Ogbeni R. A. Fani-Kayode okan ninu awon Asiwaju Egbe na.

Awon omo Egbe na fun enikokan won ni Iwe Ayesi eyiti Ogbeni S. A. Adebanjo ka si eti-gbo gbogbo enia, ninu Iwe na, awon so ero ise akikanju won ninu oran iselu eyiti o fun olukuluku omo Egbe na ni iwuri lati tele ipase awon asiwaju won wonyi. Nwon si tun fun won ni Ebun Iwe kika kookan fun iranti.

Awon mejeji si dupe lowo awon omo-Egbe na fun eye pataki ti nwon se fun won yi, nwon si so pe lilo si ilu Oyinbo awon ki ise lati lo joko tetere lairanti oran ilu awon mo, nwon ni awon tubo nlo bere ija a ti gba ominira na lehin titi ti a o fi ni isegun lori oran na ni.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon ogunlogo enia ti o pese sibi aseye na ni Alhaji Isa Williams, Oloye Bode Thomas, Oloye F. R. A. Williams, Iyaafin Bisi Akintola, Iyaafin N. A. B. Kotoye, awon Ogbeni Franco Olugbake, O Thomas, A. Adeogun, S. B. Abiola, A. Onabolu, S. B. Peters, L. Oso ati S. A. Adeyoju.

## Awon Omo Oyo Ye Balogun Si

Awon Egbe Omo Oyo "Oyo Dynamos Youths" se aseye kan laipe yi fun Oloye Bode Thomas, Balogun Oyo ni ile onje "West End Cafe" l'Eko fun ipada bo re sile lati ilu Oyinbo nibi ti awon ti se ipade atunse ofin iselu Nigeria. Dokita F. A. Akerele ni o se alaga aseye na.

Alaga na soro iwuri papo nipa akikanju Oloye Bode Thomas ninu oran ilu sise, o si so bi Balogun Oyo na ti ja fun igbega ilu Oyo to. Bakan Ogbeni S. A. Adeniyi ti o tun gbe alaga na lese tun soro apona papo nipa ise iselu Balogun Oyo na.

Oloye Bode Thomas Balogu Oyo na si dupe lowo awo Egbe Odo Omo Oyo na fu ayesi ori ti nwon se, o si k

(Wo oju ewe kerin)

**Ready For Sale**

"Tete wa ra tire ki o to tan."

LAGOS—YORUBA TOWN ALMANACK 1954

6d each, 4/- a doz. Postage extra

Apply:- I. Sho. Bankole
10, Jimoh Lane
LAGOS.

**REDIFFUSION**

FOR LESS THAN THREEPENCE PER DAY

*you can obtain*

NEWS

MUSIC

EDUCATION

ENTERTAINMENT

FROM 6 A.M. TO 11 P.M.

IN YOUR OWN HOME

APPLY AT OFFICES IN LAGOS, IBADAN & ILESHA.

## Alebu Nla Ni Ope

OPỌLỌPỌ enia ni o wa ni aiye yi-ti nwọn ko mọ pe alebu nla ni ope, ohun ti a npe ni alebu ni nkan ti ma a sọ en'a di kekere l'arin ẹgbẹ, iwa ope ni ki enia ma mọ inkan ki o ma si du lati mọ, ki o si ma a ṣe bi ẹniti o ti mọ tan, bẹni ẹniti ko mọ ti ko si gba pe on ko mọ on ni olori ope, alebu nla si ni.

Ohun ti yio ba ma alebu wa a ni lati yẹra fun un. Fun apẹrẹ lati fi han pe alebu nla ni ope, laipẹ yi ni ilu Badagry awọn kan ko ara wọn jọ, nwọn tapa si ofin Ijọba pe awọn ko ni san owo-ori ti nwọn bu fun wọn lati san, ọrọn na si di ija-igboro ti oku fi sun ti i nidi, asẹhinwa asẹhinbọ, nwọn ni lati gba lati san owo ori na nitoripe ẹtọ ati ọranyan ni lati san owo-ori.

Ṣugbọn titi di isisiyi ni awọn ti o jẹbi ẹran na fi njiya ni ọgba ẹwọn, awọn ti enia wọn si ku sinu ija igboro na ko le gbagbe lailai ohun ti o mu iparun ba ẹmi awọn enia wọn na, ohun ti o si fa gbogbo iya yi ni ope.

Bẹna na tun ni awọn ara Eruwa ni ọna Ibadan tun tapa si ofin Ijọba pe awọn ko ni san owo-ori ti nwọn fi yinbọn si awọn oniṣẹ ọba, asẹhinwa asẹhinbọ iya ni nwọn fi jẹ ara wọn, ẹnikẹni ti o ba ti lu ofin Ijọba o ni lati jiya. Nwọn si ti gba lati san owo-ori na ni irọwọ-irọsẹ nisisiyi, kosi si ohun ti o fa a ju ope lọ.

A ni lati mọ pe awa enia ilu ni a npe ni Ijọba, ki eyi le da wa loju ni a ṣe nyan aṣoju sinu Ajọ Igbimọ Aṣofin Ijọba ilu, ohun kohun ti nwọn ba si ti ṣe ni ofin ninu igbimọ ilu na a ni lati gba a ni, ṣugbọn ope ki i gba. Lẹhin ti ope ba ti jiya tan ni i to gba, a ti fi eyiti iba ṣe silẹ laiṣe a ma a ṣe eyiti iba fi silẹ laiṣe.

Ki iṣe titori ẹran ti ọdẹ pa ni iṣẹ i ma a ṣe etutu bikoṣe titori eyiti yio tun pa, nitorina alaye yi, a ṣe e fun gbogbo enia, ki ijiya awọn ope iṣiwaju le kọ awọn miran logbọn ati kọ ẹkọ rere lati ma tun fi iwa ope tapa si ofin Ijọba mọ.

Ohunkohun ti nwọn ba ti sọ di ofin ninu Igbimọ Aṣofin Ijọba Ilu, ki awọn enia ti ko ba ye to ki o bere lọwọ aṣoju wọn ninu Igbimọ na, ti aṣoju na ba si ti la a ye wọn ki nwọn gba bẹẹ ki nwọn ma tun ma a fi iwa ope ṣe ayọ ati agidi lati ma a tapa si ofin Ijọba mọ.


### WA FUN IWOSAN !

ILERA L'OOGUN ỌRỌ

[illegible] ti arun wọnyi ba mu a ja ki o wa si ọdọ mi ma a si ṣe iwosan rẹ pẹlu ogbogi ti yio le e lọ pata pata.

Iru arun bawọnyi:-

1 ẸSẸ-ỌRUN—Nko ni la a rara tabi ki nfi ogun san an ki nko wo o san.
2 ORI-YIYI tabi ỌIWERE—Mo le wo o san patapata.
3 WARAPA
4 OBIRIN TI IPỌNJU AIRI ỌMỌ SI BA MBA A JA—Ki o ma a bọ Oluwa yio fun ni ọmọ rere.
5 KOKORO ỌYAN—Emi yio yọ kokoro na ni ọjọ kanna ti o ba wa.
6 Oju riru tabi eniti ko ba riran daradara, ki o wa, ma a wo o san tan patapata.
7 Obirin ti ko ni daraqbo ti ko ba ri inkan oṣu rẹ mọ ki o ma a bọ yio si ri iwosan.
E wa dan mi wo ki ẹ si ridi otọ.

Lawani Maiyegun
(OLORI ONIṢEGUN)
3, IKOYI ROAD (Obalende) LAGOS.


E Polowo Ọja Nyin Sinu Iwe Irohin Yoruba

# Idahun Si Ibere Olotu Abukun Mb' Abuku

Lati Ọwọ S. B. Dosunmu—EKO

OLOTU, Mo ma nyin ki. Ki Oluwa Ọba ma ṣe ọba lukaye nyin. Oluwa Ọba ti o fun nyin ni ọgbọn ati oye ki o ṣe nyin. Oluwa Ọba ti a fun nyin ni [illegible] ati oye ki o ṣe nyin. Amin, fun nyin ni ohun abukalẹ. Ki o si da ẹmi si fun nyin. Amin.

Nino iwe nyin 17/8/53 ni mo ri ibere kan ti ẹ ṣe nino akọle nyin wipe "abuku ni tabi abukun," ni fun wa gẹgẹbi enia dudu nyin wipe "abuku ni tabi abukun," ni fun wa gẹgẹbi enia dudu nipa asa ti a ma oda tabi ṣe afarawe ile miran nino ire wa. Idahun temi si ibere na ni wipe abuku ni nla lo jẹ fun awa enia dudu, ati inira ti ko ni igbagbe ni ọpọlọpọ ara tabi ifarawe ma nko ba wa, gẹgẹbi apejuwe, nje enia dudu ti nyipada si enia funfun, nje bi wọn ko tilẹ sọ fun wa wipe inira wa nino rọ awa papa ko ṣa lẹ mọ wipe o nira.

E wo iba awọn obinrin enia dudu ti o nfẹ ki irun wọn dabi ti oyinbo. Ina (Fire) ni awọn ma fi ṣe e pẹlu Oriya - Irin ti o ngbona felo ni o ri ọmọluwabi ki o to le yi pada. Sibẹsibẹ ko ni dabi ti oyinbo, nje ẹ ko ri wipe awọn iru ẹni bẹ e paapa ti fi abuku ti ko ni tan kan ara wọn, ẹsyin na ẹ ti ibikan wo na, awọn ti iwe irohin sọ fun wa wipe nwọn yi pada ti alawọ funfun yi na. Ọwọ abuku ko kuro lara wọn nitoripe o ku ninu ohun dudu ara wọn ti egbogi ti awọn lo na ko le yi pada, nje iru aye wo ni ẹ ro wipe nwọn yio wa ni arin awọn alawọ funfun bayi? Bi ko ṣe ẹni yẹyẹ ati abuku. Iyen bẹ ẹ.

L ma keji asa atọwọda wa na ni a fi mba ofin Ọlọrun jẹ, nipa bayi ko si itẹlọrun fun gbogbo enia, siko ni itẹlọrun ko jẹ ki a mọ iyi ara wa. Ko si jẹki olukuluku wa gba kadara, nipa bẹ gbogbo inkan di inira fun wa. Irọrun ko si, gbogbo ohun ti a ba ti gba ni asa ni a ma nfi asẹju si, bẹni ẹtẹ lo ma nkẹhin asẹju, oko ẹtẹ na ni gbogbo awọn alasẹju wa loni yen.

E ti ibi isana kiyesi ogun, ẹ wo ọpọlọpọ awọn ọdọmọkunrin ile wa loni ni ọgba - ẹwọn, ko si ohun ti o mu wọn de ibẹ ju wipe asa-kiko ati afarawe pẹlu aiko ni igbagbọ wipe odu ti o da baba yatọ si ti ọmọ lọ, ohun ti emi ṣe ni iwọ nfẹ ṣe a ti gbagbe wipe ki iṣe-asiṣe fun Ọlọrun lati da enia kukuru yatọ si giga. Ṣugbọn gbogbo wa nfẹ jẹ enia gigun dele. Nje kini ẹ ro wipe o le kẹhin ju abuku lọ?

Nigbati ẹni ti Oluwa da wipe ki o ma a fi ẹsẹ rẹ rin ni ori ile, ki a si ma a gbadun ile Aiye rẹ nsare a ti lọ ra Mọto Ayọkẹlẹ, nje igbawo ni ko ni ri inira? Lẹhin inira a wa dẹni abuku, tabi nigbati enia ngba £10 loṣu ti o si ni ohun ti ẹni ti o ngba £20 loṣu ntẹ ni on na yio maa ṣe, nje ko ni bọ si in'a

(Wo oju ewe kẹta)



